## *Idagbasoke*

ILERA

**Ayewo tipatipa lori Kokoro-arun HIV fun awon odomobirin ile-eko ni orile-ede Malawi** — **9mins. 12secs.** — **3**
*Ipinnu ijo Olorun lati se ayewo awon odomobirin to nfe iranlowo owo lati le keko ninu ile-eko girama re ti obinrin lori kokoro - arun HIV ni o ti da awuyewuye sile.*

**Awon ipolowo Apo-ato ni a so wipe o se ponyonwu ju.** ***Olugbohunsafefe*** — **7mins. 6secs.** — **5**
*ijoba ni orile-ede Zambia mu awon ipolowo apo-ato kuro lori afefe. Ijoba so wipe won ti se ponyonnwu ju.*

AWON OBIRIN ATI AWON OMODE

**Ifi-pa-ba-omode-lopo nlosoke sii ni orile-ede Zimbabwe** — **10mins 5secs.** — **6**
*Ifi-pa-ba-omode-lopo nlosoke sii ni orile-ede Zimbabwe, isele ti orile-ede na ko le fenuko sibikan lori awon ohun to faa ati bawo ni won se le koju re.*

ISE-OGBIN ATI AABO LORI ORAN OUNJE

**Iyan tun nrokeke latari ikolu awon kokoro alajerun** — **5mins.** — **8**
*Bi orile-ede Tanzania se sese nyorun kuro ninu okan ninu awon owongogo ounje re to buru ju, orile-ede na tun ti wa labe ewu iyan miran latari ikolu awon kokoro alajerun.*

## *Ayika*

OJU-OJO

**Itankale Oju-ojo to dara sii ni orile-ede Kenya ni odun 2002.** — **6mins.6secs.** — **3**
*A o so orile-ede Kenya po mo itankale oju-ojo lati inu oko-inu ofurufu ti igbalode lati se aridaju isotele to munadoko lori oju-ojo ati lati se imu darasi imunadoko awon ilana itetekini nilo.*

IDOTI

**Ipinle Akwa Ibom ni orile-ede Naijiria se iwadi lori itudasile epo robi** — **3mins. 8secs.** — **4**
*Ijoba ipinle Akwa Ibom ni iha ila-oorun orile-ede Naijiria ti gbe igbimo ise eleniyan-mejila kan dide lati se iwadi lori itudasile epo robi ti a so wipe o sele ni ipinle na ni osu kokanla odun 2000.*

**Epo iderun fun ero agbokorin ti won ti lo tele nda isoro sile ni awon agbegbe aarin ilu** — **6mins. 7secs.** — **7**
*Titipa ti won ti ajo oloko-owo British Petroleum Zambia Plc pa ti yorisi aise idanu lona to dara fun awon epo iderun ero agbokorin ti won ti lo, eyi si nse irokeke ewu si ayika ni orile-ede Zambia.*

ITOJU

**A ko awon Rakunmi lo si Oke Kenya** — **5mins.** — **4**
*A ti pe ipe kan fun ikokuro ogogorun awon rakunmi lati oke Kenya lati yago fun ajalu ilolupo awon eda abemi ni agbegbe na.*

**Aye Ile olomi - Aye to wa fun awari** — **9mins.** — **11**
*Ogbon odun leyin Adehun Kariaye lori awon Ile olomi, ajo Ramsar polongo ojo keji osu keji odun 2001 gegebi ojo ile olomi ni Agbaye.*

**Agbegbe iyasoto Iseda-aye ni orile-ede Seychelles gba ifojusi kariaye** — **5mins. 5secs.** — **6**
*Nipa jije agbegbe iya soto iseda-aye akoko ti yio farahan ninu Odun ifojusi Ipinsiyeleyele Eda Abemi ni Kariaye, Erukusu Cousin ni orile-ede Seychelles ti gba idanimo kariaye fun irinajo afe ati isakoso etikun.*

# *Bi Mo se ri si*

AWON OBIRIN

**Imudogba Eya dara fun Ijoba Tiwantiwa** **17mins. 6secs.** **8**

*Agbejoro kan ni orile-ede Zimbabwe, Yvonne Malhunge, soro lori ojo iwaju awon obirin ninu ijoba tiwantiwa, o si se iwuri fun ilowosi to ga sii ninu ijoba.*

**Awon Eniyan wa O! Igbeowosile fun igboraeniye to dara sii.** **6mins.** **9**

*Awon obirin onkowe merin ni a ti fun ni Igbeowosile Akoki ti "Awon Eniyan wa o ! fun igboaraeniye to dara sii."*

OUNJE

**Orile-ede Democratic Republic of Congo gbe awon orisi gbaguda titun jade.** **3mins. 5secs.** **10**

*Ile-ise orile-ede Democratic Republic of Congo fun iwadi lori Imo ijinle Sayensi ati Oro aje lori Igbejade Irugbin ti se igbejade igba orisi gbaguda ti won ti danwo ni Ile-ise kariaye fun Ise-ogbin ni ile-olooru to wa ni ilu Ibadan ni orile-ede Naijiria.*

# *Ojo ati Akoko*

OHUN IMUSAGBARA

**Ohun imusagbara alalotunlo, to si se gbero gbelege ninu egberun odun yi.** **4mins. 5secs** **10**

*Gegebi oludari Alase Ajo UNEP, Klaus Toepfer, se so, awon ohun imusagbara to je ore ayika bi agbara lati inu oorun, agbara ategun, ati agbara igbi omi okun lo je okan ninu awon oran to kannigbongbon to nkoju eda eniyan ninu egberun odun titun yi.*

# *Eto Awon Omode*

**Ode na** **17mins.** **12**

*Jamina fe di ode sugbon nigbati o sonu sinu igbo, o ri awon ore titun to yi okan re ati bo se nwo aye pada.*

# *Awon Oro Asokagba*

*Se ayeye ayo iriri ile Afirika pelu awon owe manigbagbe.* **13**

# *Iroyin*

**Ayewo tipatipa lori kokoro-arun HIV 9mins. 12secs.**
**fun awon odomobirin ile-eko ni orile-ede Malawi**

Awuyewuye ti waye lori ipinnu ijo onigbagbo to powole eyiti o tobi julo ni orile-ede Malawi lati ye awon odomobirin to nfe iranlowo owo lati keko ninu ile-eko girama re fun awon obirin wo lori kokoro-arun HIV . Ijo onigbagbo ti a mo si The Church of Central African Presbyterian (CCAP) so wipe enikeni to ba fe gba iranlowo owo re ti yio kaju owo ile iwe, owo ile gbigbe ati awon ohun elo fun imototo ati igbeko gbodo jurasile fun ayewo lori kokoro-arun HIV. Awon alase ijo na tun so siwaju wipe awon to ba yege ninu ayewo akoko ti won si gba si ile-eko na yio ma ni ayewo na ni ododun fun odun mererin ti won o fi wa ninu ile-eko girama na ni ekun aala Mwanza. Awon ti won ba ni kokoro-arun ni igbakigba laarin odun merin na ni yio padanu anfani eko ofe na. Ti won ba si fe wa ni ile-eko na, gegebi ijo na seso, won yio ni lati san gbogbo owo igbeko won funrarawon.

Eto orile-ede fun Idari Arun Kogboogun Eedi (The National AIDS Control Programme (NACP) ti se apejuwe isele na gegebi eyiti o "koninirira to si nse iyasoto." Oludari ajo NACP, Owen Kalua so fun awon onise iroyin wipe eto imulo ijoba ni wipe a ko gbodo ya enikeni soto nitori wipe won ni kokoro-arun HIV. O ni "Eyi yio kan fi abuku kan awon ti koba yege fun owo iderun fun akeko na". Sugbon Eni owo Daniel Gunya, Akowe Agba fun ijo CCAP ti ekun Blantyre tenumo wipe ko si ifiyasotosi kokan ninu ilana fun owo iderun fun awon akeko na. O ni lotito, awon ti ko ba fee yio ni lati sanwo fun eko won sugbon awon to ba fe yio faramo awon ilana na. Nitorina ko si oran ifiyasoto nibe rara." Sugbon Kalua ti ajo NACP na tenumo wipe o dabi enipe ijo na so kokoro-arun HIV po mo iwa ibaje ati isekuse. O ni awon odomobirin to ti ni arun na nipa ifipabanilopo tabi ifunninieje yio jiya lainidi.

Charles Gunsaru to je oludari fun igbeko ni ipele girama ati ile-eko giga ni Ile-ise ijoba fun Eko, Imo Ijinle Sayensi ati Imo Ero so wipe ipinnu ijo na ya ile-ise na lenu. O ni "O yawa lenu nitoripe ko si eniti o tii lo ipo nini kokoro-arun HIV lati fi funni ni ohunkohun, biotileje ise, ni orile-ede Malawi." Sugbon ile-ise na to je wipe ipa alabotujo nikan ni tire, kan le gba ijo na nimoran ni. Won ko le fi agbara muu lati yi ipinnu re pada.

Eni owo Gunya so wipe o tile ya on lenu wipe iduro ijo on fa iru awuyewuye be dipo iyin fun iduro ilowosi ninu eto orile-ede fun igbejako kokoro-arun HIV ati Arun kogbogun Eedi. O ni awon asiwaju ijo so wipe eyi yio je ona kan lati fi mu awon odomobinrin wa ni mimo nipa ibalopo ki o si dena won lati ko arun apani na." O tenumo wipe, "Ayewo eje olodoodun na yio le awon omo wa sa kuro ninu isekuse yio si fun awon omo wa ni idi kan pato lati yera fun iwakiwa to le yori si kiko arun apani na."

Orile-ede Malawi lo ni okan ninu awon iye ikolu Kokoro-arun HIV ati Arun kogboogun Eedi to ga julo ni aye. Gegebi awon isiro to sese jade lati odo ajo Eto Orile-Ede fun Idari Arun Kogboogun Eedi, o to iko merinla ninu ogorun awon omo orile-ede Malawi bi milionu mewa to ni kokoro-arun to le fa Arun kogboogun Eedi.

*Africa Online*

**Itankale Oju-ojo to dara sii ni orile-ede Kenya ni odun 2002. 6mins. 6secs.**

A o so orile-ede Kenya po mo itankale oju-ojo lati inu oko-inu ofurufu ti igbalode ni odun to nbo. Itankale titun na, ti yio sise fun awon orile-ede to sese ndagbagba soke marundinlaadota, ni a fi lole ni Erekusu Guyana to wa ni ilokuro ni etikun ila Iwo oorun ile Afirika.A lero wipe itankale na yio se aridaju imunadoko awon ilana itetekinimilo. Ogbeni Ajub Shaka to je adele Igbakeji oludari Eto Iwoju-ojo so wipe, "A o le fun awon onibara wa ni ifitonileti to peye ti a si se ni ibamu pelu inilo won." Nigbati o nba iwe iroyin The

Nation soro ninu yaara ise re, Ogbeni Shaka so wipe imo ero titun lori isotele yio pese imo lori oju ojo ni iyara ilopo meji ti ilana isisinyi, eyi yio si jeki a le ma topase awon iyipada oju-ojo. Itankale oko inu ofurufu titun na, eyiti yio sise fun Europe ati Afirika, yio ma gbe imo jade ni iseju meedogun meedogun dipo idaji wakati bi o se wa nisisiyi.

Eka Ile-ise Orile-ede Kenya fun Iwoju-ojo ni yio se akoso akoso akoko imurasile fun ise agbese na awon orile-ede Afirika, Caribbean ati Pacific to nkopa ninu re. Gegebi Ogbeni Shaka se so, Ajo Ile Europe ti fowosi igbekale owo lati jeki awon orile-ede na mu awon ibudo oju-ojo won ba ode oni mu. Orile-ede Kenya yio se igbekale ibudo kan fun gbigba imo lati inu oko inu ofurufu ki o si ko irin-ise titun si awon ibudo akojo-imo re kakiri orile-ede na lati le mu won wa ni ibamu pelu imo-ero titun na. Ise agbese na yio da awon onimo ijinle ati onise-ero nipa oju-ojo leko gegebi ara eto kan to ti nlo lowo fun odun meta seyin. Ibudo Itopinpin Ogbele ti orile-ede Kenya, eyiti nsise fun ekun IGAD, ni yio ni anfani bakanna lati ara alekun agbara lori imo-ise ati imo-ero. Gegebi Egbe ile Europe fun awon Oko inu Ofurufu fun Iwoju-ojo se so, itankale titun na ni a lero wipe yio fun ni ni ifitonileti ilopo ogun ju eyi ti oko inu ofurufu Meteosat nfunni nisisiyi. Yio ni ibudo imo mejila dipo meta ti Meteosat ni, eyiti yio si ma gbe aworan to ja gaara sinu afefe lori awon isele oju-ojo ni awon agbegbe kokan . Ajo fun oju-ojo ni ile Europe na so wipe awon imo ti o ba gbejade ni a le lo lati fi mu idari fun awon Oko Ofurufu lagbara sii, ati idabobo fun awon oko irinna oju omi.

Itankale oko inu ofurufu titun na, eyiti a lero wipe yio ti ma se gbogbo ise to ye ko se ni odun 2005, ni yio ma se ilowosi si itopinpin awon isele ayika bi isodiasale, iyipada afefe ile ati awon ina.
*The Nation*

**Ipinle Akwa Ibom ni orile-ede Naijiria se iwadi lori itudasile epo robi. 3mins. 8secs.**

Ijoba ipinle Akwa Ibom ni ila-oorun orile-ede Naijiria ti gbe igbimo-ise eleni-mejila kan, ti ojogbon Etie Akpan onimo ijinle sayensi lori ilana ile ni abe omi, je olori won dide lati se iwadi lori itudasile epo robi ti a so wipe o sele ninu osu kankanla odun 2000 ni ipinle na .Alakoso ile-ise ijoba ipinle na fun Ayika, Obong Isidore Akpan-Ebe, nigbati o nba awon oniroyin soro, so wipe “iroyin to nde ile-ise yi toka si wipe nitoto itudasile to po gididgidi sele ni awon etikun ipinle na.”

O ni won ti fun igbimo na ni ose mefa lati fi gbe iroyin re fun ijoba. O tun so wipe “Ni afikun, igbimo tun nsise lori awon aworan lati inu oko ninu ofurufu ti a gba lati awon ibudo itopinpin eyiti a gbekale ni awon ibiti o se pataki lati le ma fi topinpin ayika ipinle Akwa Ibom to gbelege”.

Awon alase-ajo Exxon ati Mobil ni osu kokanla odun to koja ti so, leyin ti won mu awon oniroyin lo ninu irin-ajo kan lori okun ati etikun, wipe ko si itudasile kokan ni ipnle na. Alakoso na to daruko ajo Exxon ati Mobil, Elf ati Shell gegebi awon ogunna gbongbo ajo to nsise epo robi ni awon etikun ipinle Akwa Ibom, so wipe Igbimo-ise lori awon itudasile na yio so laipe eni to ni awon ibudo-ise nibiti awon itudasile na ti nsele. Obong Akpa-Ebe fi da awon ara ilu loju wipe bi igbimo Ojo gbon Etie Ben Akpan ba ti pari ise re, gbogbo abajade re ni a o gbe jade fun awon ara ilu.
*all Africa.com*

**A ko awon Rakunmi lo si Oke Kenya 5 min.**

Alakoso Egbe Afenifere Ibori Igbo (The Greenbelt Movement). Ojogbon Wangari Maathi ti kepe fun ikokuro awon ogororun rakunmi kuro ni Igbo Oke Kenya. Ojogbon Maathai ti kowe si olori awon osise lori awon darandaran. O ni awon eranko na yio da ilana ilolupo awon eda abemi agbegbe na to se pataki pupo je. O ni ilana ilolupo agbegbe yi to je ile eti odo ni a gbodo dabobo ni onakona. O ni, “Ikolo awon eranko na sinu igbo na lo nso kikankikan wipe isodiasale ni orile ede Kenya ti de ibi to derubani. Eran asale ni awon rakunmi”.

O ni iyan ati ebi yio di isele ojojumo ni orile-ede Kenyna ti a ko ba dabobo awon igbo, nitoripe awon lo nfa ojo to nse atileyin ise ogbin, pupopupo. O nso ero re lori iroyin wipe awon darandara ti nda ogogorun rakunmi si iha Gathiuru ninu igbo oke Kenya lati wa papa ijeko. Ifilodi si be tun wa lati odo asoju agbegbe Kieni ninu ile igbimo asofin, Dokita Chris Murunguru ni agbegbe eniti Gathiuru wa. Sugbon kiakia ni ijoba fesi awon darandaran na. Oga awon olopa ni Nyeri, Elijah Shamalla se ibewo si agbegbe na lati se agbeyewo ipo ti idaabobo wa leyin awon iroyin to so wipe o nseese ki ija sele laarin awon darandaran ati awon agbe to ngbe ni agbegbe na.

Ojogbon Maathai fesi si oro Igbakeji oga olopa Agbegbe Laikipia, Omar Sallat to so wipe awon darandaran na kan nda eran na kiri ninu ipaya ni. O ni “O ye ko mo wipe awon miran wa to ni ipaya lati dabobo awon iparun awon igbo na. Ojo ati Irugbin ti kuna latari iparun awon igbo, eyi lo si fa a ti ebi fi npa awon omo orile-ede Kenya.”
*The Nation*

**Awon Ipolowo Apo-ato ni a so wipe o se ponyonwu ju 7mins. 6secs.**
Ipolongo lati koju kokoro-arun HIV ati Arun Kegboogun Eedi ni ifaseyin nigbati olugbohunsafefe Ijoba ni orile-ede Zambia mu awon ipolowo apo-ato ti ijoba so wipe o se ponyonwu ju koro lori afefe. Awon asiwaju ijo onigbagbo lati inu Igbimo Kristeni ni orile-ede Zambia to je egbe oluparowa to lagbara lara eyiti awon ijo alagbara bi melo kan wa, ti gbe ohun awuyewuye soke wipe awon nkan ipolongo ni ikoju Arun Kogbogun Eedi ti Ajo orile-lede Zambia fun igbohunsafefe (Zambia National Broadcasting Corporation)gbe sori afefe laarin awon osu bi melo kan seyin ni ko tona to si nse iwuri fun isekuse.

O dabi wipe ijoba funrarare ko fenuko lori oro naa. Minisita fun ilera, Enoch Kavindele so ni ose to koja pe o ye ki awon asiwaju esin Kristeni “ dojuko otito bi ikan se wa” lori bi ajakalearun Eedi na ti gbile to, sugbon minisita fun Eko, Godfrey Miyanda gbe leyin awon eniyan Olorun na. Aare Frederick Chiluba, eniti o kede Zambia gegebi Orile-ede Kristeni ni odun 1991, so wipe on ro wipe ilo apo-ato je aami ailekoraeninijanu lori ibalopo. Ipinnu ajo ZNBC lati fagile awon ipolowo na - ti won se ibowo fun ero awon ara ilu - ni awon olupolongo ni idojukoArun kogboogun Eedi ti bu enu ate lu. Masauso Nzima to je alakoso ti orile-ede fun Ajo Alasepo ti Arun Kogbogun Eedi to fikale si orile-ede Geesi so wipe o dabi enipe “ awon eniyan ko mo bi ikolu Kokoro-arun HIV ati Arun kogboogun Eedi ti po to ni orile-ede yi” O fikun wipe: “ Apo-ato lo je okan ninu awon ona pataki lati se idena itankale Arun kogboogun Eedi, mo si ro wipe ko ye ki won kan sonu bayen laiko funni ni ifiropo.

Isiro iko ogun ninu ogorun awon omo orile-ede Zambia to je agbalagba lo ni kokoro-arun HIV. Gegebi isiro ti ijoba funrarare se so, o ju edegberin egberun eniyan lo ti ku latari awon idi to je mo Arun Kogboogun Eedi lati odun 1980, awon omode to le ni egbegberun lona egbeta o le adota ni o ti di omo orukan. Ni lowolowo yi, awon omode ti iye won lo lati egberun meedogbon si ogbon egberun ni won nbi pelu Kokoro-arun HIV ati Arun kogboogun Eedi, nigbati awon meje ninu mewa awon omode yi ni a ko nireti wipe yio se ayeye ojo ibi won ikarun.

Bi o se njewo awon eewo isedale lori isoro lori ibalopo ni gbangba, Nzima so wipe on gbagbo wipe ariwo to waye lori apo-ato na sele nitoripe awon ipolongo na ni won gbe safefe lakoko ti opo eniyan ngbo redio “ nigbati awon obi njeun ale pelu awon omo won. O seese ki akoko na ma dara to sugbon mo gbagbo wipe ohun kan wa ti a npe ni itoni obi”. Ijo Kristeni ti nparowa iseraeni gege bi ojuutu si ajakale-arun Eedi.

Nils Gade to je oga agba fun Egbe fun Ilera Ebi ti orile-ede Zambia salaye wipe Eto Ajo Agbaye lori Arun Kogboogun Eedi, iyen ajo UNAIDS ti “ fowosi apo-ato gegebi ona to munadoko julo lati yera fun Arun kogbogun Eedi - paapa fun opolopo awon omo orile-ede Zambia ti ko mo ipo ti won wa, boya won ni kokoro arun na tabi won ko ni.”
***intergrated Regional and Information Network***

**Ifi-ipa-ba-omode-lopo nlosoke sii ni orile-ede Zimbabwe 10mins. 5secs.**

O ju egberun meji ejo ifi-ipa-banilopo pelu awon omode ti ojo ori omiran kere to osu meta ti won gbe wa siwaju awon ile-ejo ni odun to koja ni orile-ede Zimbabwe. Awon alase ati awon egbe ilu gbagbo wipe tente ori apata yinyin si ni eleyi. Ifipa ba awon omode lopo nlosoke sii ni orile-ede na, isele ti orile-ede na kole fenuko sibi kan lori kini o faa ati bawo ni won sele fowo mu u. Ni opolopo igba , awon omode a ni ifipabanilopo lati odo awon ebi to ye ki won ko won le lowo fun itoju, eyi si ma njeki iwa-ibaje na soro lati mo. Sugbon ohun to nko awon alase ati awon egbeegbe obirin ajafitafita lominu ni isele to sese nyoju ninu eyiti iwa odaran na nwaye lati owo awon ti awon onisegun ibile ti gbanimoran lati fi pa ba omode sun lati le gba iwosan kuro

ninu aisan ti kogbogun. Igbagbo awon afipabanilopo ati awon onisegun ibile na ni wipe iwani mimo ara ati okan omode ni anfaani egboogi, nigbamiran ke, won a ma huwa odaran na ni ireti wipe yio mu orire bawon.

Abajade re ti je nkan ibanuje fun olufaragba ati awon obi re. Opolopo ninu awon omode ti won fipa balopo ni won nko arun ti ibalopo ntankale ran, lara eyiti Arun Kogbogun Eedi wa. Iwadi fihan wipe o to iko adorin ninu ogorun awon omode olufaragba ifipabanilopo ti won nfun ni orisi arun ti ibalopo ntankale kan tabi omiran.

Awon isiro tokasi wipe laarin awon egberun marun eniyan to nni ikolu Arun Kogboogun Eedi losose ni orile-ede naa, iko ogbon ninu ogorun won loje omode ti yio ti ni iriri ibaje lori ibalopo. Aikitetele mo iba omode je lori ibalopo, latari ayika ile nibiti opolopo ifipabanilopo na ti sele, ma nsi awon olufaragba na sile fun ikolu arun. Egbe ajifitafita kan, Ise agbese lori Omode ati Ofin (Child and Law Project), siro wipe opo ninu isele ifipabanilopo na ma ndi mimo leyin odun kan, ti olufaragba ko ba ni ipalara kokan tabi ikolu arun lati inu iwa ibaje na. Awon iwadi miran tokasi wipe ifipaba awon omode lopo gbile ni oride-ede na tobe ti o fi je wipe opo ninu awon omodebirin ni Zimbabwe lo ti ni imolara nipa ibalopo lati igbati won ba ti di omo odun mejo, to je idaji ojo ori fun ifaramo labe ofin. Igbimo oluwadi kan ti Aare Robert Mugabe gbe dide di odun meji seyin ri wipe opolopo ninu awon omodebirin lo ngbe labe irokeke ifipabanilopo nigbagbogbo, o si wa tanmo awon ofin. to le pupo lati fi daabobo awon omode na. Igbimo na ninu iroyin re so wipe: " Isele iru eyi (ilosoke ifipa ba omodelopo) je ohun ikanni gbongbon nitori ewu to fi awon omode na si lati ko awon ikolu ti ibalopo ntankale (Sexually Transmitted Infections) ati kokoro arun HIV."

Sugbon orile-ede ko iti mo dajudaju, leyin opolopo iwadi lori ifi-ipa-ba-awon omode lopo, idi re ganan ti isele ifipaba omode lopo to nsele ni awon igberiko patapata paapa ti orile-ede na fi nlosoke. Bi eri lati ile-ejo ninu awon ejo ifipa-ba-omode-lopo se ntokasi ilosoke ilowosi awon ilowosi onisegun ibile ninu iwa odaran na, awon onisegun na njiyan wipe igbile asa awon oyinbo lo nfaa.Awon egbe obirin ajatafitata so wipe iwa odaran na nigbilesi nitori ijiya ti ile-ejo nda fun odaran na ko leto lati da awon eniyan lowoko kuro ninu ifipa-ba-omode-lopo. Won nkepe fun idajo iku fun awon afipabanilopo, tabi ju eyi lo, iteloda, ijiya meji ti won ro wipe o kun oju osuwon bi iwa odaran na se buru to, ti yio si je idanilowoko toto.

*Pan African News Agency*

**Agbegbe Iyasoto Iseda-aye ni orile-ede Seycheelles gba ifoju si kari aye 5mins. 5secs.**

Erekusu Cousin ni orile-ede Seychelles ti gba idanimo kariye fun irin-ajo afe ti ilolupo eda abemi ati isakoso etikun leyin ti o ti di agbegbe iyasoto fun iseda aye akoko iru re ni ile Afrika ti yio kopa ninu odun Ifojusi Ipinsiyeleyele Eda Abemi ni kariaye. Awon iroyin to de ilu Port Louis so wipe Agbegbe iyasoto pataki ti Erekusu Cousin ni won damo gegebi apeere to dara julo ni bi won se nseto irin-ajo afe to jemo ilolupo eda abemi ati fun isakoso etikun ati omi okun ninu atejade meji ti awon ajo kariaye gbe jade laipe yi.

Agbegbe Iyasoto pataki na, eyiti ajo Birdlife Seychelles nsakoso re, ni apeere kansoso to wa ninu iwe na ti a pe oruko re ni "Idagbasoke Alagbero ninu Irin-ajo afe: Akosile awon ise rere lati Ila-oorun Afirika ati ekun Iwo-oorun okun kariaye ti India." Ninu iwe kan to ko si Minisita orile-ede Sychelles fun irin-ajo afe ati igbokegbodo oko Baalu, Simone de Comarmond, Akowe-agba Ajo WTO, Francesco Fragialli so wipe: "O da mi loju wipe iwe yi na yio se afikun si iyi okowo irin-ajo afe ni orile-ede Seychilles." Iwe keji - Awon Agbegbe idabobo lori Omi ati ni Etikun - Itosona fun awon Oluseto ati Alakoso" ni Egbe Isokan ni kariaye fun Itoju Iseda Aye gbe jade. Erekusu Cousin yo ninu awon isele alafiyesi meji pataki to wa ninu iwe titun na. Ikinni to se afihan isakoso erekusu na ni a pe ni " Erekusu Cousin - Agbegbe Iyasoto okun ati Erekusu ti ajo afenifere ti ko lowo ijoba ninu nsakoso lona imo ijinle Sayensi. O se apejuwe awon aseyori ninu iwadi, ibojuto, eko, isakoso ati eto sise.

Nirmal Ji van Shah ti o je oga agba ajo BirdLife Seychelles so wipe itan aseyorisirere erekusu na tan imole si orile-ede Seychelles lapapo, ati wipe gbogbo omo orile-ede Seychelles loye ko ma yangan lori awon aseyorisi na. Shah ni: " Awon eniyan ni orisirisi ero nipa awon nkan, sugbon okan ninu awon ona to daraju lati fi se idiwon oriree ati aseyorisi rere ni ifiowosi ati idanimo lati odo awon ajo kariaye ti aye mo daada. A ko ni sinmi lori aseyori wa, sugbon a o tesiwaju lati ma fi awon aseyege titun lele ni Erekusu Cousin ati i bo miran."

*All Africa com.*

**Epo iderun fun ero agbokorin ti won ti lo tele nda isoro sile ni awon agbegbe arin ilu** **6mins. 7secs.**

Awon epo iderun fun ero agbokorin ti won ti lo tele ndoju ewu titun ko ayika ni orile-ede Zambia. Teletele, ajo British Petroleum Zambia Plc ma nra awon epo iderun na pada fun atunse ni ile ero won to wa ni ilu Kitwe to wa ni aringbungbu agbegbe ti won ti nwakusa fun baba. Sugbon nigbati won ti ile-ero na pa, awon ile-ise ati ibudo itun-oko-se kan ma nda awon epo na nu bo se wu won, ti eyi si nsopo mo orisun omi mimu.

Gegebi Jewitt Masinja to je Akowe Agba ni ile-ise ijoba fun Ayika ati oro Adayeba se so. " Epo iderun ti ati lo tele gbodo je ohun ikannigbongbon to ga lori ayika nitori awon eroja kemikali ati ti abuda to wa ninu re jeki o lewu fun idarasi awon ile, omi ati afefe. " Nitori idi eyi ni ile-ise fun Isakoso Egbin ni Gusu ile Afrika eka orile-ede Zambia se gbe idanileko oniifioroweoro kan kale laipe yi ninu eyiti koko oro agbeso je bi won se nda epo iderun ti won ti lo nu. Awon to tun pese ni awon osise lati awon ibudo itun-oko-se ati awon ajo oloko-owo to nta epo robi. Ero awon to gbe idanileko na kale ni lati se ayewo iri ikolu ti epo iderun ti won ndanu lati awon ibudo itun-oko-se ati awon ibudo ti won nti ta epo moto nni lori ayika.

Leyin ti won ti ti ile-ero itunse epo ti ajo BP Zambia to wa ni Kitwe ti won si gbe lo si orile-ede Zimbabwe, awon ibudo itun-oko-se ati ibudo ita-epo beresi tu epo danu laibikita sinu awon koto idominu gerege ati awon koto miran. Nigbamiran awon epo yi ma nsan lo si ibi omi mimu, ibi idaegbinsi ati oko-ogbin ati awon ile to wa legbe awon ibudo itun-oko-se ati ita-epo paapa. Abajade eyi ni wipe epo na ti ba omi ti awon eda eniyan ati eran-osin nlo je o si ti pa awon eda abemi ninu omi run, lara awon ti a ti ri eja ati awon opolo to nje efon.

Nisisiyi, ile-ise na nsowopo pelu awon eka to wa ni orile-ede South Afrika, Namibia, Zimbabwe, ati Botswana lati se agbekele ilana imusese lati se iwuri fun atunse awon epo iderun ti a ti lo tele ki o ledi ohun elo to dara. Ireti ni wipe ona agbero lati din egbin ati ibaje ayika laibikita nipa dida epo iderun aloku nu ni a o yera fun tabi dinku repete.

*Pan African News Agency*

**Iyan tun nrokeke latari ikolu kokoro alajerun.** **5mins.**

Bi orile-ede Tanzania se sese nyorun kuro ninu okan ninu awon owongogo ounje re to buru ju, orile-ede na tun ti wa labe ewu iyan miran latari ikolu awon kokoro alajerun. Ijoba ti kede wipe marun ninu ogun ekun oke-ile orile-ede Tanzania ni awon kokoro alajerun na ti yabo, ti mefa miran wa labe ewu ikolu. Awon agbegbe ti oran kan ni Dodoma, Arusha, Mbeya, Iringa, ati Singida, nibiti awon kokoro na ti nposi lona tobanileru. Meta ninu awon ekun na - Arusha, Kilimanjaro ati Tanga - ba orile-ede Kenya paala ni iha ariwa, iberu si ni wipe ikolu na le ya wo inu Kenya. Ifoya tun wa wipe ikolu lati Mbeya le ya wo awon orile-ede Malawi ati Zambia to je alamulegbe. Bi otilejepe Ile-ise ijoba fun Ise-ogbin ati Aabo lori ounje ko le so pato bi ibaje na se to ni idiwon tonnu, isiro re nlo ni ogogorun egberun iwon tonnu oka ninu awon oko-ogbin to gba ile bi saare hektari egberun meje o le okoodin legberin ni awon ekun mararun na. Ijoba orile-ede Tanzania ngbaradi lati bere fun millionu kan owo dola Amerika lowo Ajo Agbaye fun Ounje ati Ise-ogbin (UN Food and Agriculture Organisation) ni ilu Rome lati fi dojuja ko irokeke kokoro alajerun na. Ni akoko yi kan na, Tanzania ti ni idojuko ikolu lati owo awon esu pupa, eku ati awon eye quelea ti awon osise ijoba so wipe ti won ko ba daduro o le tubo ba aabo onje orile-edeTanzania je.

Osise kan ni eka idabobo Ile-ero, Ogbeni Sergei Mutahiwa, kilo fun awon orile-ede to ba die ninu awon ekun to ni ikolu na paala wipe ki won mura sile nitori irinkiri awon kokoro na le gba igbelarugbe lati owo oju-ojo ati ategun.

*The East African*

## *Bi mo se ri si*

**Imudogba Eya dara fun Ijoba Tiwantita** **17mins. 6secs.**

Aibikita awon ondibo lo ti je ohun to ma nsele ninu idibo ni orilede-ede Zimbabwe lati odun 1985, eyi losi faa ti awon osise to seto ti idibo odun to koja si ile igbimo asofin fi jewo wipe titujade awon ondibo ya awon lenu pupopupo. Leyin idibo ti odun 1980, idunusubuluayo ominira poora bi oju awon eniyan se wale ti won si dojuko bi ikan se wa gangan. Awon eniyan ko kan ridi lati dibo. Awon obirin, gegebi ara awon ondibo, na kan tele itesi yi . Pipo ti awon obirin po ju okunrin mu ki won je ile olora fun enikeni to ba gbero lati di omo ile igbimo asofin ninu idibo kan. Sugbon nje a tile ka awon obirin si gegebi ondibo? Abi won ti fi won sipo awon akorin ninu ipolongo awon okunrin fun idibo ? Se titi laelae ni ati fi won sipo pe ki won maa korin ki won si maa kunle sori paapa ibale ni Idiko Balu Harare ki won ma wo gareta ori oko oloko ? Dajudaju asiko ti to lati ka awon obirin to ni agbara ifobaje si eniyan pataki. Se ko ye ki awon egbe oloselu ma wa ibo won tagbaratagbara ?

Gegebi ondibo awon obirin gbodo se alekun imo won lati ye itan egbe oselu kan wo ati eto imulo re lori eya nitorina ohun ti koseyera fun ni wipe bi egbe oselu kan bati pe si ni akosile re nipa aikobiara si oro eya ninu ipolongo idibo yio se gun to. Otito kikoro ni orile-ede Zimbabwe ni wipe to ba je pe gbogbo awon obirin to leto lati dibo ni lo ti forukosile lati dibo, ti gbogbo si dibo fun egbe kan, egbe na ko nilo ibibo eyokan soso lati odo okunrin ki o to ni awon omo egbe to poju ninu ile igbimo asofin. A nso eyi lori wipe ati fokansi wipe ko ni si ese ofin orile-ede to fun Aare ni ase lati yan ogbon (Okunrin) omo ile igbimo asofin. Ohun to je otito to banininuje ni orile-ede Ziimbabwe nipe nitori bi agbekale awon egbe oloselu seri, awon obirin ko ti le kopa ninu igbe aye oloselu ti orile-ede yi ni awon ona to se pataki bi ti okunrin.

Oran to se pataki julo ni orile-ede Zimbabwe ni wipe ayika ko fararo fun awon obirin.Iselu ni a ti pe ni ere “ Idoti” Jakejado aye ati ti o je wipe okurin nikan lo nse. Obirin to ni ibowo fun ara re ni a ko lero wipe ko lowosi ere yi. Lakopo, nigbati enikan bati pinnu lati di osise ijoba, oniyen funrarare yan, ki ise lati fo awon aso re nita gbangba nikan, sugbon pelu “iranlowo” awon alatako won ninu oselu, ki won si sa awon ti ko mo daada ninu awon aso na sita gbangba fun ayewo awon ara ilu.

Won ti jiyan re wipe ilowosi awon obirin ninu oselu ye ko jeki iselu mu otito dani si ki o si fojusi awon oran yato si awon eniyan. Ni oride-ede Zimbabwe, idoti oju-ona ipolongo ma nfi ara re han ni ona to se wogowogo. Eyi ni nipase iwa-ipa oloselu jakejado orile-ede na. Otito to buru nibe ni wipe gbogbo ayika na ntenumo wipe eni to ba lagbara julo ni yio ruura. Bi o se je wipe awon obirin to laapon ninu atako ni won doju iwa-ipa oloselu na ko, eyi je iranleti fun awon obirin na wipe ki won mase lowosi iselu. Bi o tun se je wipe awon obirin nkopa ni ipele ti isale ninu awon egbe alatako, won ki ise awon ti wo ndibo fun, ntenumo alaigbara won rara.

Ohun miran, ninu igbeyewo temi, ti won tun ti lo fun ipalara awon obinrin, ti o si mu ki awon obirin to nwa ipo oloselu dinku, ni eto isedale ati ilana ibuyifun. A ma nmomo tabi ni aimo tumo eleyi sodi si ipalara awon obinrin. Nitorina a ma nkoko wo awon obinrin gegebi obinrin ki a to wo won bi eniti a le fakale. Agbeyewo ipo won ni o nwaye: on nikan lo wa ni tabi o ti loko? ti ko ba iti loko, idi re ti ko iti loko? Se o ti koko sile tabi beko? Nje o ti bimo? Okunrin melo lo bi won fun? A kii ibere awon ibere wonyi nipa awon okunrin oloselu. Lotito, ohun to je itewogba ni fun okunrin oloselu lati wa lori iyawo keji tabi iketa. A si rii gegebi enito lowo. Ipo obinrin to ndu ipo ni a ma nso di koko oro idibo, ki ise agbara re lati koju awon isoro agbegbe na. Ninu aye to wa ni deede, odikeji ni ohun to tona. Lotito, ninu awon obirin ondupo die ki itile le rekoja ilana iyaniyan laarin egbe won nitori awon itumo odi wonyi.

Nipa ilowosi mi ninu idibo sinu ile igbimo asofin, mo mo bi ipolongo fun idibo se ma nna ni lowo to. Ni orile-ede Zimbabwe opolopo inawo lo ma nwaye nipase egbe oselu awon oludije. Ninu Zimbabwe ti o peye, o ye ki omo orile-ede Zimbabwe kokan le gbe owo, akitiyan tabi ohun ini re miran sile fun egbe oselu ti o wuu. Ayafi ti egbe oselu kan ba ni awon ona to daju lati fi ri owo gegebi eyi ti a fi idaniloju si labe ofin egbe oloselu (Isunna), bi beko, yio soro fun iru egbe be lati ri owo. Pelu e na, otito wipe egbe oselu kan ti ri owo ko tumo si wipe awon obirin oludije laarin egbe na yio gba igbeowosile ni dogbadogba pelu awon okunrin oludije. Eyi ni idi ti o fi se pataki fun awon obi lati fi ara won sipo to se pataki laarin awon egbe won.

Ijoba to ba gba lati se agbekale ayika fun imudogba eya pelu isejoba rere ati ijoba tiwantiwa je eniti o sowon fun wa gidigidi, nitorina bi ijoba kan ba ni obinrin kansoso ni ipo minisita agba, agogo ikilo awon obinrin ondibo gbodo pariwo ju iro itolerawon oko ayokele to ngbe aare ati awon emewa re lo. O gbodo je ijoba logun, ki ise lati se igbelaruge ayika to fi oro eya sero, o nikan, sugbon eyi to tenumo isepataki asepo onidogbandogba laarin awon okunrin ati awon obinrin ninu awujo olominira ati ti onijoba tiwantiwa.
*Ageku Erongba Yvonne Malhunge ninu iwe iroyin Zimbabwe Independent.*

# *A ti gbo*

**Awon eniyan wa O! Igbowosile fun Igboraeniye to dara sii** **6mins.**
Awon obinrin onkowe merin ni a ti fun ni Igbeowosile Akoko ti “Awon Eniyan wa O! fun Igboraeniye to dara sii”. Igbeowosile na ni a se lati inu owo to wole lati inu “Awon eniyan wa o!” iwe ti gbajugbaja kariaye onise iroyin omo orile-ede India, Alka Raza, ati iyawo Asoju orile-ede America si Naijiria tele, Susan Twaddell, ko lati saami odun awon Agbalagba ti Ajo Agbaye., O se akosile itan igbesi aye awon agbalagba omo orile-ede Naijiria lati orisirisi eka, lati ogbontarigi onise iroyin de obinrin to nlu ilu ibile. Gegebi Alejo pataki, oludari Ekun fun Ajo Amuludun ti Ford, Dr. Akwasi Aidoo, se so, igbeowosile na je ayeye lati ko afara saarin awon ewe ati agbalagba omo orile-ede Naijiria, awon to nrekoja ise ona nitori ise ona funrarare ......... awon ti won nife ninu idagbasoke ........... awon obirin onkowe to dangajiya to si ni ebun .......... to nife lati so itan ti orile-ede Naijiria.” Igbeowosile akoko fun iwe na lo waye lati odo ajo Amuludun ti Ford.

Daniel Landry, asoju kan fun Ajo Agbaye fun oran iye Eniyan Ilu (United Nations Population Agency) tun fi ironu kanna han nigbati o wipe "Awon alejo lati kariaye, le nigba miran, woye nipa ayika ju awon olugbalejo won lo nitori eniyan ma nwa ti kosiniri awon iwe to funni ni irisi ti a ko kun ni awo ti a ko si se pelu isegbe nipa awon eniyan ilu won .....(iwe na) fi awon aseyori awon eniyan ilu to je eniyan pataki ati eyiti ko ni oruko lawujo han.

Awon ti a gbe owo fun ni a yan lati soju awon ekun pataki orile-ede na. Nneka Osakwe je omo iha ila-oorun to nsise oluko ni ile eko giga Yunifasiti Nnamdi Azikwe ni Awka, o si je eniti o ti gba opolopo aami eye ti orile-ede ati ti kariaye, o si je ajifitafita fun eto awon omode. Ititaka lati oke oya ni a jewo re nipase elewi ati oluko awon itan kuukuku, Binta Muhammed Florence
Inokweje ni obirin aringbugbun ti a yan nitori ise re ninu ewi, ere ori itage, itan awujo ati awon ipolongo odo. Iyaafin Kemi Olaitan, olukopa. Ninu ere itage, onkowe sinu iwe iroyin ati alakojo eto lori redio to je ohun to ga soke ninu ija fita fita fun eto awon obinrin, soju iwo - oorun. Okankan ninu awon to gba owo yi ni a fun ni ogorun egberun Naira lati se atileyin akitiyan won ki won s\i gbe ise won jade ninu imo awujo ati oro aje.
*CFC*

**Orile-ede Democratic Republic of Congo** **3mins. 5secs.**
**gbe orisi gbaguda titun jade**

Ile-ise orile-ede Democratic Republic of Congo fun iwadi lori Imo Ijinle Sayensi ati Oro aje lori Igbejade Irugbin ti se igbejade igba orisi gbaguda ti won ti danwo ni Ile-ise kariaye fun Ise - ogbin ni Ile-olooru to wa ni ilu Ibadan ni orile-ede Naijiria. Awon orisi gbaguda na ti o sese ko ba afefe-ile agbegbe mu ni won yio tunse po sii ti won yio si pin won fun awon agbe agbegbe. Ile-ise na so wipe ninu eyi, ayewo awon ibudo itoju ojele irugbin meji to wa ni Mwazi ati Mbakana, ni eyin odi ilu Kinshasa, ti bere. Ibudo kini ni won gbekale pelu iranlowo ile-ise na, nigbati ikeji gba atileyin lati odo Ibudo Ise-ogbin fun Idagbasoke Alasemuwonuarawon to wa ni Mbakana (Mbakana Agricultural Centre for Integrated Development) nibiti won gbin egberun lona ogorun awon ege to yege daradara. Igbejade ati ayewo awon orisi titun yi wa ni ibamu pelu
akitiyan ijoba orile-ede Congo lati pa awon kokoro gbaguda run.

Gbaguda ni ounje to po julo fun awon to ju iko aadorin ninu ogorun lo ninu omo orile - ede Congo, paapa ni awon ekun Bundudu ati isale-odo Congo, ati ninu ilu Kinshasa. Awon akitiyan wonyi, eyiti o ni atileyin Ajo Agbaye fun Ounje ati Ise-ogbin, ni a se laarin ilana ise agbese kan ti a fokansi lati se igbekale ona ti yio wa titi fun imudarasi aabo ounje.
*Pan African News Agency*

**Ohun Imusagbara alatunlo to si se** **4mins. 5secs.**
**gbero gbelege ninu egberin odun yi**

Gegebi Oludari Alase Ajo UNEP, Klaus Toepfer, se so fun ipade kan lori ohun imusagbara alagbero, awon ohun imusagbara to je ore ayika bii agbara lati inu oorun, agbara ategun, ati agbara igbi omi okun lo je okan ninu awon oran to kannigbongbon to nkoju eda eniyan ninu egberun odun titun yi,, O kilo wipe, "Agbara ina to ba ayika mu ni a gbodo fi sinu aarin idagbasoke alagbero ti a o ba koju irokeke iyipada iyipada afefe-ile ati igbogunti osi ati ailera ninu iha aye to sese ndagbasoke nitooto. "Idagbasoke alagbero tabi aiseru fun awon omo yin, tumo si awon nkan bi sise aridaju wipe awon ilu nlanla wa sise bi ibi to wunilori to si dani laraya lati gbe ati lati sise; ati lati se aridaju wipe awon eniyan to talika ju laye ko ha debi ti won o fi ge gbogbo igbo nibiti awon eda abemi egan to sowon pupo wa lule fun igi lati fi dana tabi mu ara won gbona".

Awon ero wonyi ni a mu siwaju ninu ipade Igbimo Amusese ti Ajo G8 lori Ohun Imusagbara alalotunlo kan to waye ninu osu kini odun yi bi awon minisita lati orile-ede Afirika mewa to pejo ni ile-ise ajo UNEP Nairobi fohunsokan lori ipo kanna lori ilo alagbero fun ohun imusagbara. Awon minisita na yio gbe awon abajade won fun ipade kesan ti ajo fun idagbasoke Alagbero ti yio waye ninu osu kerin odun. Awon imoran Toepfer tun waye ni ifojusi ipade kokanlelogun ti

Igbimo Alase ti Ajo UNEP ninu eyi ti awon minisita jakejado aye yio pade ni ilu Nairobi lati ojo karun si ikesan osu keji odun yi nigbati ohun imusagbara alalotunlo to se gbero yio je awon koko oro ti yio wa lori ise agbese fun igbimo na

*Pan Africacn News Agency*

**Aye Ile Olomi - aye to wa fun awari** **9mins.**

Awon olubere to yege lati mu aseju awon orile-ede mejidinlogun wa si ilu kekere kan, Ramsar, ni orile-ede Iran, ni etikun Caspian ni ipari osun kinni odun to je osu olotutu ni idi lati gberaga lori ohun ti won se nigbana. Adehun Kariaye lori Ile-Olomi ni won sasepari re ninu ipade na ni ojo keji osu keji. Loni, leyin ogbon odun, adehun na ti di ohun imulo to munadoko eyiti awon egbegbe olusise metalelogofa nlo lati se aridaju itoju ati ilo ologbon fun awon ile olomi won. Awon oju ewe die yi to ni igbese mejila to je akosile Adehun Ramsar ni o ti yeje lati se idasile igbese lati daabobo okan ninu awon ilana ilolupo eda abemi to ni ibisi to poju to si wa labe irokeke ewu lori ile aye yi.

Awon odun to ti koja ti fihan wi pe Adehun Kariaye lori Awon Ile Olomi rekoja ohun elo ofin kariaye ti a nlo; o je egbe nla kan to ni awon omo-eyin to ti fi ara ji, iyen awon ajo ijoba , awon awujo onimo ijinle sayensi, awon ajo kariaye, awon eniyan ibile, awon ajo ti ko lowo ijoba ninu, laarin orile-ede ati ni kariaye, awon egbeegbe agbegbe ati awon logaloga ninu awon ile ise adani paapa. Ninu awujo yi ni a ti ri okun ati imunadoko Adehun kariaye lori awon Ile Olomi, nkan pataki ti a gbodo naani ki a si mu alagbara sii bi a se nteriba fun awon ofin ere eyikeyi ninu awon adehun onijobasijoba.

Awon orile-ede to je omo egbe metalelogofa, awon ibudo egberun kan o le metalelogoji lori itosile awon Ile Olomi to se pataki kariaye eyiti o gba ile to fere to egberun lona egberin ibuso kilomita ni igun mererin re ti ile Olomi, to je aayo agbegbe ile olomi awon orile-ede pupo to ni awon ofin tabi eto ise to dara lori ile olomi, orisirisi awon ohun elo ise ati eto imulo ti a se ninu ilana adehun na ti a si fi ase si lati owo apero awon egbegbe. Eyi ni otito to wuni lori nipa Adehun Kariaye Ramsar loni. Sibesibe, a ko iti le sinmi. Opolopo awon ibudo Ramsar lo wa labe irokeke ewu, opolopo ninu won ko si ni ilana isakoso to munadoko nile. Awon ofin imulo lori awon ile olomi ni awon orile-ede bi melo kan kan wa ni akosile lasan ni, bena si ni awon Alase ise Ramsar ni awon orile-ede miran ko ni okun rara debi wipe won tile le mu ayipada wa ninu eto imulo ati ise awon ajo ijoba miran to je wipe awon ni won ni agbara to poju lori oro ile olomo ni orile-ede na.

Lati le koju awon aleebu wonyi, a ni lati mu opo eniyan ati awon eka awujo si i wo inu egbe Ramsar. A ni lati se ju bi a se nse lowolowo lo lati ran awon eniyan lowo lati se awari iwulo awon ile olomi ati awon ise won, ki a le ri opo oludaabobo sii ti a le gbekele nigbati o ba de ibi yiyan awon ijoba ati didari awon ipinnu lori isakoso awon oro adayeba. Eyi ni koko ifokansi ojo Awon Ile olomi ni agbaye fun odun 2001, eyiti oro akomona re je, "Aye Awon Ile olomi - Aye to wa fun Awari". Ojo keji osu keji odun 2001 ni ojo ti o wa fun awon eniyan lati se awari iwulo ati awon ise awon ile olomi na. Nipa sise eyi a o se ilowosi pataki kan si mimu ilera ilolupo awon eda abemi lori ile aye wa - ilekansoso na ti a gbogbo jijo ni - wa ni deede.

*Delmar Alasco, Akowe Agba fun Ramsar*

# *Eto Awon Omode*

**Ode Na** **17mins.**

Ni owuro kutukutu, Jamina ba baba re agba lo lati lo ko oyin. Won tele eye oyin wo inu igbo jina rere. "Mo fe ri erin" Jamina kigbe, "Baba Agba, se e ro wipe a o ri won?"
"O le sorire," baba arugbo na dahun. A ki i ri opolopo won mo nisisiyi, paapa lati igba ti awon ode ti de." Awon ode! Oju Jamina tanna. "Ode ni emi na yo je". Jamina beresi sere ode, o yin ibon fun erin nla, o topase agbanrere kan wonu igbo jinjin, o yo gologolo tele egbe awon kiniun kan, o yi pada lati wo baba re agba. Sugbon o ti sere wonu igbo lo jinna, baba re agba ati eye oyin na ko si si nitosi mo. O kigbe soke sugbon gbogbo re palolo. Nigbana, lati inu ategun jinna rere, o gbo ohun kan, igbe ibanuje ati ipaya to fa okan re. O seemi o si tetisile. Jamina woke. Awon eye igun wa loke ninu oorun osangangan na, besi ni o ni ifura wipe ewu wa ni ayika.

"Ma maa da lo sinu igbo," awon obi re ti ki i nilo sugbon ohun to ngbo na jo ti ipohunrere ekun tobe ti ko fi si ohun to le se ju wipe ki o topase re lo. O lo titi titi ....... titi titi ti o fi de ile gbalasa kan. Nibe ni o ri omo erin kekere to ngbinyanju lori asan lati ji iya re. Awon ode ti sise won, gegebi Jamina, omo erin na ti sonu, eru si nbaa. "Ma sokun mo, eni kekere, Jamina soro kelekele. Jamina yi ori segbe kan lati gbo boya awon erin to ku wa nitosi. Sugbon nkan to gbo ni yun-yun-yun ariwo awon kokoro ninu ooru na. O mo wipe ikoko na ko le ruula ni on nikan. O le gbiyanju lati mu lo sile, o si seese ki won ri awon obi re lona. Sugbon eru nba ikoko na. "Emi ki ise ode." O soro jeje fun igba pipe, o ba erin na soro titi ti ara re fi bale ti o si fi owo ija re paa lara. Jamina dide duro o si gbe igbese bi melo kan. Ikoko na telee, o ntogege ninu ooru gbigbona na. Nigbana ni ojo de, bi omi si se mu ara re tutu,erin na ni okun lati tesiwaju. Ni awon igba miran, won a yo, won a si jijakadi sugbon won nrin lo laarin iji na. Bi oju orun se ka, ara erin na ya, Jamina si ro, ni akoko na, wipe on ngburo awon erin. Sugbon nigbati o duro lati tetisile ohun to ngbo ni kikun ategun ninu awon koriko. Fun igba pipe erin na ko lati tesiwaju. Leyinna, pelu ibanuje ati idakeje o tesiwaju.

"Ti o ba sonu", baba re agba ti so fun, "tele awon egbe eranko ni osan; won yio mu o lo si odo. Ile wa ni odi keji." O pe ki Jamina ati erin na to ri egbe ketekete abila kan to nla ile perese na koja lo. Nwon rin tele awon eranko na ti ongbe ngbe ni gbogbo osan gbigbona na. Bi oorun se nlo sile loju orun, nigbeyin gbeyin won de odo na. Sugbon awon oju to farasin nwo won lati inu odo na, Jamina si ni ifura wipe ewu wa nibe. "Ibi yi lewu lati koja, eni kekere, a gbodo tesiwaju," Jamina so fun erin na . Bi Jamina se yiju pada o ro wipe on nri awon erin lokeere. O seju o si ranju re, sugbon awon igi acacia nikan lo wa lokankan ti ewe won ntan yinrinyinrin ninu imooru ojo na. Jamina ati erin na tun tesiwaju, sugbon laipe ikoko na bere si fa seyin. "Ko jinna pupo mo," Jamina bebe, sugbon o ti re ikoko na ju wipe ko tesiwaju lo. Bi Jamina ti duro pelu re, o ronu nipa iya re. Bo baje pe o le pee. Laipe awon eniyan yio beresi kominu; Laipe won yio beresi wa kiri. Ikoko na soro kelekele. O fowo pa lara jeje. Ko ni iya to le pe mo "Tetisile!" Jamina pa erin na lenu mo. Won ngbo ohun awon eniyan. Awon obi mi! o ro ni okan re. Sugbon awon ojiji to nri ni okankan na ki ise awon obi re. "Awon ajiodese !" o rora soro pelu iberu. Nisisiyi Jamina na dabi okan ninu awon eran-ode. O gbadura wipe ki ikoko na ma ke. Sugbon erin ni ifura ibi, on na si duro rigidi titi ti ewu na fi koja. Okunkun de, gbigbo ati hihan awon eda oru si bersi gbe ifoya wonu egungun Jamina. O kajo sunmo ikoko na, o tun wa di mo pelu iberu bi igbe to dayafoni kan lati odo nkankan ti ebi npa se dun nitosi.

Bi Jamina ti nduro fun atako, oro baba re agba tun to wa lekan si . "Nigbakugba to ba wa ninu ewu, mase so ireti nu". Nitorina Jamina tetisile fun awon obi re. O di oju re, o si bere si fi okan fe won. Sugbon dipo won, awon erin ni o ri. Okan re kun fun awon egbegbe erin atijo. Awon owoija nlanla ti baba re agba ti ri nigbati o si wa ni odo. Awon erin nlanla to nlo bi anjonu la awon ile perese na ja. O si ngbo kikun won jeje to rinle nitosi. Nigbati o la oju re, awon erin po yika, bi enipe o pe won ninu ala re. Eru o ba Jamina.

O ni, “mu eni kekere yi kio si paamo lalafia.” Nigbati o fi ma di imole kinni ni owuro, iya Jamina ri nibiti o gbe nsun lori koriko. “Mo nsere ode mo si sonu.” Jamina so fun un. Pekipeki lo sunmo iya re titi ti won fi dele, nigbati won de abule o so funrara re kelekele. :Ngo ni di ode laelae.

*Paul Granty ninu iwe “Ode Na”*

## *Awon oro Asokagba*

Se ayeye ayo iriri Ile Afirika pelu awon owe manigbagbe wonyi.
Lori ogbon
*Ma se lo irole ninu ile ti o ko setan lati sun si*
Orile-ede Ethiopia

*Mase bu ooni nigbati o ba wa leti odo*
Orile-ede Uganda

Lori Suuru
*Adie ki iwale pelu ese mejeji*
Orile-ede Equitorial Guinea

*Suuru ni eyin to npa eye nlanla*
Orile-ede Zimbabwe
*More African proverbs*

................ Nisisiyi, oro kansoso lori itoju
Eni to ba ngbin igi feran awon elomiran yato si ara re
Thomas Fuller, 1723

Ranti............
Okan dabi eweko, o nhu sibi to ba wu u
Orile - ede Zimbabwe
*African proverbs*